ISAAA
INTERNATIONAL SERVICE FOR THE ACQUISITION OF AGRI-BIOTECH APPLICATIONS

# Ipo Ti Awon Ohun Ogbin Imo-Ero Ti O Ye Fun Tita Wa Lagbaye: Ti Odun 2013

**Onkowe Ni Clive James, Ti O je Oludasile Ati Alaga Ana Ti Ajo ISAAA**

*A ko eyi lati saami ayeye ojo ibi oloogbe Norman Borlaug ti o pe ogoorun odun ni (25th of March 2014), eni ti o gba ami eye Nobel Peace Laureate, ti o si je oluldasile ISAAA*

---

**KOKO MEWAA TI O GA JULO nipa eto ogbin imo-ero(Biotech) ni odun 2013**

**KOKO KINI. 2013 je odun kejidinlogun aseyori okoowo eto ogbin imo-ero biotech. Odun 1996 ni a koko ta awon ohun ogbin biotech.** Ni odoodun, laarin 1996 si 2013, saare ti a fi nsogbin imo-ero biotech npelekee si pelu lilesi ni ogoogorun fun odun mejila gbako, eyi to n safihan ifokanbale ti ogunlogo awon agbe ti o ti foju wina eto ogbin yii ni ninu re lagbaye, yala lorileede to sese ngoke agba tabi awon onileese nlanla.
Lati igba akoko ti a ti s'ogbin yii ni odun 1996, saare oko ti a nlo ti gbe peeli sin ni ona ti o wuyare, eyi to ju bilionu kan abo saare, iwon agbegbe bii ida aadota ninu ogoorun ti o ju ile China tabi United States lo.

**KOKO KEJI. Saare oko imo-ero biotech gbe peeli si ni ilopo ogoorun lati milionu kan abo-lerugba(1.7million) saare ni odun 1996 si milionu marundin-logoosan (175million)saare ni odun 2013.** Eyi lo mu ki ona eto imo ogbin Bt di itewogba laipe yii -kini idire –won ni ere to po jojo. Ni odun 2013, saare ohun ogbin biotech le sii ni iwon milionu marun-un, pelu idagbasoke ida meta ninu ogoorun lodunlodun. O ye lati kiyesii pe awon ere odoodun ati sisogbin lori apata ti a ti sotele pe yoo ri bee fun bii odun melo kan, latari itewogba ohun ogbin biotech ti ko fayegba imugboro(laarin ida aadosan ninu ogoorun si ida ogoorun ninu ogoorun).

**KOKO KETA. Iye awon orileede to sogbin imo-ero biotech ati akojopo ohun ogbin oto.** Ninu awon orileede metadinlogbon to sogbin lona imo-ero biotech ni odun 2013, mokandinlogun je orileede to sese ngoke agba, nigbati mejo je orileede to nileese nlanla. Akojopo ohun ogbin oto gba saare metadin-logbon ninu ogoorun.

**KOKO KERIN. Ni igba keji ni odun 2013, awon orileede to sese ndagba sogbin saare to po ju orileede to nileese nla-nla lo.** Ohun to se Pataki nipe, orileede to sese ngoke sogbin imo-ero biotech ni odun 2013(ni iwon ida merin-le-laadota ninu ogoorun) ti o tumosi (merin-le-laadorun milionu saare), *94 million hectares* ju awon onileese nla nla lo niwon ida merin-din-laadota ninu ogoorun(milionu mokanlelogoorin saare) *81million hectares*. Idowopo araalu ati olodooni ni a sagbekale re ni awon orileede bii: Bangladesh, Brazil ati Indonesia.

**KOKO KARUN-UN.Iye awon agbe to n sogbin imo-ero biotech.** Akosile fihan pe ni odun 2013 milionu meji-din-logun awon agbe(18million) to ju idameji milionu kan ti 2012 lo sogbin biotech leyi to ju ida aadorun ninu ogoorun tabi iwon to ju milionu merindinlogun abo, awon wonyii je agbe to kuse ni awon orileede to sese ngoke. Awon agbe lo mo bi a se nsagbefo ewu ati bi a se nte siwaju ninu kikore nipa hiho koko mo ona ti a fin sagbe yii(eleyi to fi oko dida si bilionu kan abo saare fun ogbin sise ti o si ndaabo bo awon aginju ati awon ohun abemi to wa layika). Ni odun 2013 bakanna, akosile fihan pe milionu meje abo (7.5million)agbe kereje ni orileede China ati milionu meje-le- oodurun(7.3million) ni India ni a dibo yan lati gbin owu Bt sori saare oko to ju milionu meedogun lo, nitori ere ti o joju ti won nri nibe. Ni odun 2013 ti a n wi yii, o to bii irinwo egberun awon agbe kereje to janfaani agbado Bt ni orileede Philippines.

**KOKO KEFA. Awon orileede marun ti o leke ninu sisogbin imo-ero biotech-nipa sisagbekale Agbado ti eerun kii baje ati akojopo soyabeans ti HT/IR.** Orileede US l'o si n gbegba oroke pelu aadorin-le-legberun saare oko ti o wa ni ibamu pelu ida aadorun ninu ogoorun oniruuru awon ohun ogbin gbogbo ti won yan lati gbin. Patakijulo, egbewa awon agbe ni orileede US lo sogbin agbado ti eerun kii baje ni ona ogbin imo-ero biotech fun igba akoko, sori saare oko ti o to egberun lona aadota. Orileede Brazil lo se ipo keji, l'odun marun leralera ni o fi je pe oun ni awokose ni gbogbo agbaye latari bi o se lopo saare ti o fi nsogbin imo-ero biotech ju orileede miran lo – akosile to wuni lori ni iwon bii milionu meta abo-lerugba saare, eyi t'o gbe peeli pelu ida mewa ninu ogoorun ni odun 2012 pelu ogooji milionu le-loodunrun saare oko. Orileede Brazil yii kanna tun sogbin soyaHT/IR ni igba akoko lona ti o tayo pelu milionu meji-lerugba saare, ewa ti ndena kokoro arun, ti a gbin labele pelu imo-ero biotech ni o ti wa fun tita. Orileede Argentina si wa nipo keta ti o wa teleri pelu milionu merin-le-logun-o-le irinwo saare. India to ropo Canada ni ipo kerin l'akosile fihan pe O sogbin owu Bt sori saare oko to to milionu mokanla pelu itewogba ida marun-din-logoorun ninu ogoorun. Canada ti o wa ni ipo karun-un lo sogbin biotech sori milionu mewa-o-le egberin saare ti o ni atewogba ida merin-din-logoorun ninu ogoorun pelu adinku ogbin Canola. Ni odun 2013, okookan awon orileede marun-un t'o leke lo sogbin to ju milionu mewa saare, eyi t'o npese aye to gbooro ati ipile rere fun ogbin ojo ola.

**KOKO KEJE. Ipo ti awon ohun ogbin imo-ero biotech wa ni ile Adulawo(Africa).** Afirika si n tesiwaju latari anfaani ti orileede Gusu Afirika(South Africa) nje fun bii odun mewa ninu awon ohun ogbin imo-ero biotech. Ogbin saare Owu Bt ni orileede Burkina Faso ati Sudan gbe peeli si ni ida aadota ninu ogoorun fun Burkina Faso ati ida oodunrun ninu ogoorun fun Sudan ni odun 2013. Ninu igbese ti o kehin si ifontelu tita ohun ogbin biotech, awon orileede meje(Cameroon, Egypt, Ghana, Kenya, Malawi, Nigeria ati Uganda) ni won lo si papa lati mo awon eyi t'o dara julo. Patakijulo, ise ti WEMA nse l'o sagbekale agbado ti eerun ko le baje, akoko iru re, ti a gbin ni ona imo-ero biotech fun orileede Adulawo fun odun 2017. Aini isakoso ti o niise pelu imojinle Sayensi, to gun rege ti ko nani lowo tabi gba akoko eni yoo maa je idena fun itewogba ilana eto ogbin yii. Isakoso to wuyi, ti a fi taratara se sugbon ti ko mu iyonu lowo ni awon orileede kekeeke, ti osi nta, ti o sese ndagba nilo.

**KOKO KEJO. Ipo ti awon ohun ogbin imo-ero biotech wa ni EU.** Akosile fihan pe orileede EU marun-un(Spain, Portugal, Czech Republic, Slovakia ati Romania) sogbin agabdo biotech sori saare oko ti o to egberun lona meji-din laadojo eyi t'o gbe peeli pelu ida meedogun ninu ogoorun ni odun 2012. Orileede Spain nleke ajo EU pelu saare bii metadin-logooje egberun ti won fi sogbin agbado Bt, o gbe peeli ni ida mejidinlogun ninu ogoorun ni odun 2012 nipa akosile ida mokanlelogbon ninu ogoorun itewogba ni odun 2013.

**KOKO KESAN. Awon anfaani ti o ro mo awon ohun ogbin imo-ero biotech.** Laarin odun 1996 si 2012, awon ohun ogbin imo-ero biotech mu ki onje po ya-n-turu, o si tun mu ki oju ojo ati ayika duro deede nipa: mimu ki ohun ogbin po si ni iye owo to to billionu merin-din logoofa-o-le milionu mesan Dola(US$116.9billion), o si nseto ayika to dara nipa didin ilo oogun apa kokoro ku ni iwon aadorun-le-nirinwo kilo(497kg): ni odun 2012 nikan, o din afefe oloro CO2 ku ni iwon billionu merin-din-logbon kilo ti o dogba pelu kiko millionu mokanla-o-le egberin moto kuro loju popo fun odun kan; didaabo bo awon ohun abemi ti o wa layika pelu ididaabo bo saare ile to to millionu meta-le –logoofa ni odun 1996 si 2012; ati didin osi ku nipa riran awon agbe kereje ati awon ebi won to ju millionu merindinlogun abo lo lowo, eyi ti gbogbo re ju millionu marun-din-laadorin eniyan lo; ti won wa lara awon eniyan to tosi ju lagbaye. Eto ogbin imo-ero yii se Pataki ni tooto, sugbon kii se ona abayo ati titeramo sise agbe lona ti o dara bii akore-dare-si ati fifun ohun ogbin lagbara atidena akolukogba se pon dandan fun ohun ogbin Bt bi o se pon dandan fun awon ohun ogbin miran.

**KOKO KEWA. Agbekale ojo iwaju.** Ki a maa nireti pe ojo ola yoo dara pelu awon ere ti a n ri lodun nipase itewogba ti o to ida aadorun ninu ogoorun tabi ju beelo fun awon ti o se Pataki lara ohun ogbin imo-ero biotech t'o wa loja lopolopo, ni awon orileede ti o sese ndagba ati onileese nlanla. Bangladesh, Indonesia ati orileede Panama ti fi onte lu s'isogbin biotech ni odun 2013 pelu imurasile fun oro aje re ni odun 2014.

Ajo ti ko duro de ere, ti awon araalu ati awon aladani n fowo ran lowo ni ISAAA je.Eekan pere ni a ka gbogbo awon saare oko ti a fi sogbin imo-ero(biotech) ti a ko sile ninu awon iwe ISAAA, laifi ti iye adamo/akanse ti awon ohun ogbin naa ni se. Ekunrere alaye wa ni ISAAA Brief 46**"Ipo Ti Awon Ohun Ogbin Imo-Ero Ti O Wa Fun Tita Wa Lagbaye: Ti Odun 2013,** ti Clive James ko. Fun ibeere e wo ori ero ayelujara ti http://www.isaaa.org tabi ki o kan si ISAAA SEAsia Centre pelu nomba yii +63495367216, tabi ISAAA AfriCentre pelu +254204223618 tabi **africenter@isaaa.org**.